# Àwọn Tó Nbéèrè Fún Ààbò Àgbáyé

**Abala Àkọ́pọ̀**

Ní Bank of Ireland, à ń fi ara wa yangàn nípa bí a ṣe ń  mú ìgbéláruge bá ìgbáyégbádùn àwọn oníbàárà wa ní ti ètò ìṣúná.  Kí àwọn èèyàn le gbádùn ètò ìṣúná, gbogbo èèyàn gbọdọ̀ nípa nínú ètò ìṣúná. Ìyẹn sí túnmọ̀ sí pé oníkálukú gbọdọ̀ láánfàní sí àwọn ohun tó níí ṣe pẹ̀lú ètò ilé ìfowópamọ́. A ń ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn tí ó ń béèrè fún ááàbò àgbáyé nípa jíjẹ kí wọ́n lànfààní sí àwọn ohun tó níí ṣe pẹ̀lú ilé ìfowópamọ́ àti rí ríi dájú pé wọ́n rí àwọn àtìlẹ́yìn iṣẹ́ ètò ìṣúná tí wọ́n nílò gbà nípa ṣíṣe ìtunmọ̀ àwọn iṣẹ́ wa.

A ní àwọn èròjà méjì tó jẹ́ kòṣeémáàní ní ibi iṣẹ́ ìfowópamọ́ lójoojúmọ́ èyí tó máa wúlò fún àwọn tó ń béèrè fún ètò ààbò àgbáyé; akantì aládáni oní ìwé sọ̀wédowó pẹ̀lú akantì alábọ́ọ̀dé, tí méjèèjì sì ń fún ẹnikẹ́ni ní ààyè láti fi owó pamọ́ kí wọ́n sì ríi gbà. A pèsè àwọn àlàyé nípa ọ̀kọ̀ọ̀kan akantì wọ̀nyìí pẹ̀lú àtòkọ àwọn ìwé tí a nílò láti ṣí àwọn akantì yìí.

Nígbà tí o bá ti ní gbogbo ìwé tí a béèrè fún, o lè wá sí èyíkéyìí nínú àwọn ẹ̀ka Bank of Ireland ká lè bẹ̀rẹ̀ ìgbésẹ̀ láti ṣe àgbékalẹ̀ akantì rẹ tuntun. O tún lè ṣí akantì aládáni lórí ẹ̀rọ ayélujára.

Ó yé wa pé àwọn oníbàárà kan lè má ní ìmọ̀ èdè Gẹẹ̀sì kankan tàbí kí wọ́n rò pé ìmọ̀ wọn nínú èdè Gẹẹ̀sì lè má kún tó láti dáhùn àwọn ìbéèrè nígbà ìbẹ̀wò sí ẹ̀ka kan. Bọ́rọ̀ bá rí bẹ́ẹ̀, inú wa dùn láti sọ fún ẹ pé o lè mú ọ̀rẹ́, ojúgbà tàbí atúmọ̀-èdè kan dání pẹ̀lú rẹ láti túmọ̀ èdè fún ọ.

Ní àfikún, púpọ̀ nínú àwọn òṣìṣẹ́ Bank of Ireland ni wọ́n ń sọ ju èdè kan lọ, inú wa máa dùn láti wá bí a ṣe lè pèsè ìranlọ́wọ́ tí kò bá sí ẹnikẹ́ni tó lè bá ọ ṣe ìtúnmọ̀. Sá ti béèrè Olùdámọ̀ràn Ìkíni Kú Àbọ̀ ní ẹ̀ka náà.

O lè rí àwọn àlàyé nípa àwọn ẹ̀ka wa níbí  https://www.bankofireland.com/branch-locator/